M05/1/A1YOR/HP1/YOR/TZ0/XX

22050341

**YORUBA A1 – HIGHER LEVEL – PAPER 1**
**YOROUBA A1 – NIVEAU SUPÉRIEUR – ÉPREUVE 1**
**YORUBA A1 – NIVEL SUPERIOR – PRUEBA 1**

Tuesday 3 May 2005 (morning)
Mardi 3 mai 2005 (matin)
Martes 3 de mayo de 2005 (mañana)

2 hours / 2 heures / 2 horas

---

INSTRUCTIONS TO CANDIDATES

- Do not open this examination paper until instructed to do so.
- Write a commentary on one passage only.

INSTRUCTIONS DESTINÉES AUX CANDIDATS

- N'ouvrez pas cette épreuve avant d'y être autorisé(e).
- Rédigez un commentaire sur un seul des passages.

INSTRUCCIONES PARA LOS ALUMNOS

- No abra esta prueba hasta que se lo autoricen.
- Escriba un comentario sobre un solo fragmento.

*Ko àgbóyé re lórí òkan ninú àwon àyokà méjì wònyí*

**1.** (a)

# (17) PÀSÁN TÍ A FI NA ÌYÁÁLÉ

Gégé bí ó ṣe jé pé ẹyẹ tó lẹ́wà tó Ọ̀kin kò sí nínú igbó, ti ó sì jé pe ẹranko tó dára bi egbin kò wọ́pọ̀ nínú ijù, bẹ́ẹ̀ nàáa ni obìnrin tí ó dára tó Amọ́roro di ṣàṣà ni àarin ọmọ adárihunrun.

Ó jé ẹni pupa, èyi ni wọ́n fi n pè é ni Amọ́roro. O kúrú, ṣùgbọ́n ó sanra mọ̀ kúkúrú yìi, sísanra náà kò pọ̀ tó eyi ti o le bà á jé. Eyin ẹnu rè funfun dáadáa, èji kan si wà láàrin àwon eyin isalẹ̀, èyí ló fi kun ẹ̀wa náà.

Ki i ṣe pe Róro (gẹ́gẹ́ bi àgékúrú orúkọ rè) dára lásán, ṣùgbọ́n ó tún ni ọ̀yàyà pẹ̀lú. Ẹ̀rín kì í wọ́n lẹ́nu rẹ̀ nígbà kan, bi ó bà si ti fẹ eyin ni eji ìsàlẹ̀ yii máa n bùkún ẹwà ẹnu rẹ̀. Ìdílé Olówó ni Roro ti wá.

Lótiitọ́ iyá rẹ̀ ti kú ni àsìkò ìtàn yii ṣùgbọ́n àwon ẹ̀gbọ́n rẹ̀ mẹ́rẹ̀ẹ̀rin ti wón dìjọ jé ọmọ ìyá ni wọn rí jẹ. Bàbá Roro náà ti fẹ̀yinti lẹ̀nu iṣẹ́ ijọba ṣùgbọ́n ó ti ṣiṣẹ́ ọ̀dá silẹ̀ lásik òjò ẹ̀wa.

Ṣe bi ọpọ̀ ọmọbinrin bá lẹwà, ti wọ́n si tún ti ilé ọlọ́lá wá báyìí, gàarù wọn máa n pọ̀ ṣùgbọ́n Roro kò sí nínú wọn. Ìwà ìrẹ̀lẹ̀ tirẹ̀ kò ṣe fi ẹnu sọ. Ṣùgbọ́n ẹyin adiẹ dára títí, ṣùgbọ́n kò lójú, ejò wuyi láwọ̀ ṣùgbọ́n ọ̀rọ̀ rẹ̀ kù si ibi ìwà ìkà, ajá òyìnbó yáàyì títí ọrọ wá kù si àti ṣe ọdẹ, àni omo dáadáa kò rí ọkọ rere fẹ́.

Láti igbà ti Amọ́roro ti wà nílé ẹ̀kọ́ giramọ ni àwọn onímọ́tò bọ̀ọ̀kù, bọ̀ọ̀kù ti n yọ ọ lẹ́nu ṣùgbọ́n ẹ̀ẹ̀kan ti ó wò wọ́n ọ̀dájú, ẹlẹ́ẹ̀keji àbùkù ni, àni kò fi ìfẹ́ rẹ̀ fún wọn. Ṣùgbọ́n nígbà iyọlẹ́nu àwọn ọkùnrin pọ̀ jù ohun tí o yẹ lọ, ó gbà láti fé Boro.

Boro yii jẹ ọderẹ̀rẹ̀ ènìyàn, gùdùgùdù ṣe ojú dẹ̀ẹ̀rẹ̀ fi pa ọmọ jẹ si ni pẹ̀lú. Ṣùgbọ́n ojú ni ẹ̀dá rí Olódùmarè ló rínú, àṣẹ alágbàṣe Roro ti si oko gbà, Bóro náà jé arẹwà Ọkùnrin ṣùgbọ́n iwà àgbèrè àti fùkẹ̀ asán ti jàrábà rẹ̀.

Bí ó tilẹ̀ jé pé Boro kò kà ju iwe mẹ́wàá lọ, ó ti di ẹni ti o n lo mọ́tò fàáji nibi iṣẹ́ rẹ̀. Nígbà ti Roro si fi má a lọ fún ẹ́kọ́ ìjìnlẹ̀, ọ̀rọ̀ òun pẹ̀lú Boro ti wọ̀, wọ́n tilẹ̀ ti mọ̀ nípa ìfẹ́ wọn ní ilé àwọn méjèèjì.

Ki Roro tó lọ fún ẹ̀kọ́ ìjìnlẹ̀, wọ́n ti jọ ṣe àdéhùn pe bi ó bá ti pari ẹ̀kọ́ náà ni awọn yóò ṣe ìgbéyàwó. Ọpọ̀ àwọn oniwèè bọ̀ọ̀kù bọ̀ọ̀kù lo n

yọ Roro lẹ́nu ní èkó ìjìnlè ti ó lo sùgbón òun ti ní oko ló n so fún won.

Ṣùgbọ́n kò ju oṣù mẹ́fà ti Boro tún fi bá ọmọbinrin kan pàdé. Pupalàntà ni orúkọ obìnrin náà. Ó pupa gidi, diẹ̀ ló si kù kí ó di àfín. Nígbà ti yóó si fi tó ọdún kan tí wọn ti mọ ara wọn ìfẹ́ wọn kò tilẹ̀ tan iná mọ́ tí ó fi n riran. Boro n lọ sí ilé ẹ̀kọ́ Roro lẹ̀ẹ̀kọọkan ni, Làntà (àgékúrú Pupalàntà) ni ó wà lórí ẹ̀mí rẹ̀.

Nígbà tí Roro jáde, òun pẹ̀lú Boro ṣe ìgbéyàwó, wọ́n si náwó nibi àṣeyẹ náà ayé gbọ́, ọ̀run sì mọ̀ pẹ̀lú. Ṣùgbọ́n kò jọ́ tipátipá ni Boro fi fẹ́ Roro ni, nítorí pé àwon ará ilé rẹ̀ k fọwọ́ si pé ki ó fi Roro sílẹ̀.

Bi Làntà ti gbọ́ pé Boro ti ṣe igbeyawo pẹ̀lú omidan kan ló ti fi ààké kọ́rí pé ifẹ́ àwọn ti dé òpin. Ṣùgbọ́n Boro tí kò kẹ̀rẹ̀ ni ibi ọgbọ́n àyídé rọ tútù si i nínú, ó si fi ye e pé òun yoo yẹra fún ìyàwó náà láipẹ́.

Ọpọ̀lọpọ̀ owó ti Làntà ri gbà lọ́wọ́ Boro àti ọkọ fàáji, tí ó ni kò jẹ̀ ki ó lè fi i sílẹ̀. Ṣùgbọ́n kì í ṣe pé óókòó lásán, nṣe ló lọ sílé onísègùn ti yo o ba a yọ ìfẹ́ Roro ni ọkàn Boro.

Roro jẹ́ Olóòótọ́ ìyàwó, gbogbo owó oṣù rẹ̀ ló sì n kò fún Boro. Boro náà a si fi i mu ọtí, èyí tí ó bá kù ni yóò kó fún Làntà. Owó yíì kan náà ni Làntà n kó fún onísègùn.

Kò ju ọdún kan lọ lẹ́yìn ìgbéyàwó ti Boro fi sọ pàsán di oúnjẹ Roro. Bi ó bá ti ti òde ọtí dé ló máa n lu Roro ni àlùpọ̀jẹ̀. Ṣé òògùn Làntà ló n ṣisé. Nígbà tí àwọn ẹ̀gbọ́n Roro kò fẹ́ pàdánù àbúrò wọn ni wọ́n bá mú àbúrò wọn sọ́dọ̀. Nígbà tí Ọlọ́run kò sì ti fi ọmọ sí àárín wọn kiákiá ni wọ́n tú igbeyàwó ká.

Oṣù kejì ti wọ́n tú ìgbéyàwó ká ni Làntà kó wá inú ilé Boro. Olúwa si fi ọkọ alálùbáríkà kan ta Roro lọ́rẹ. Kò si mú oṣù tí ó dé lé ọkọ náà jẹ tí ó fi lóyún. Ṣé ìwà kò ní fi oníwà sílẹ̀ láéláé kò ju ọjọ́ kẹ̀ẹ̀dógún ti Làntà dé ilé Boro ti Boro tún fi bẹ̀rẹ̀ sí wá àlè kiri igboro. Ṣùgbọ́n ẹran nlá ni tàkúté rẹ̀ gbé. Obinrin ọ̀gbọ́dẹ̀dẹ̀-gbẹrù kan báyìí ti o ti di egungun ìlú ló fẹ́.

Kò si pẹ́ tí ó dé ti ó fi fi òògùn kan náà fọ́ ojú Làntà méjèèjì. Báyìí ni alágbèrè okùnrin se kan idin nínú iyọ tí pàsàn tí a fi na ìyáálé sì tún wá di ohun ti a fi naa ìyàwó pẹ̀lú. Àṣé ohun gbogbo ló ní ẹ̀san.

Olatunji Opadotun, OjaOkunkun ati Awon Itan Miran,
(Onibon-Oje Press and Book Industries Nigeria Ltd, Ibadan, 1988)

**1.** (b)

## ÀJÒ À-RÈ-Ì-BỌ̀

Ìwọ Olígbàgbọ́-ẹnu, o kò ńwòran i?
Ìwọ Olùfẹ́aiyé, o kò ńrí gbogbo rẹ̀ i?
O kò ńrí bí ọdúnnì ti ṣe, o kò bẹ̀rù àjò àrèìbọ̀ i?
Pípẹ́ rèé ó máa pẹ́, àgbọ̀nrín á bọko;
Pípẹ́ rèé ó máa pẹ́, à á bá'ra-ẹni lọ̀kànlèji,
L'ájò àrèìbọ̀!
Àjò àrèìbọ̀!
Ìwọ Olígbàgbọ́-ẹnu, lọ dé Bẹ́rì k'o w'ògbóni rẹ,
Líbi ó nìkàn sùn l'ájò àrèìbọ̀,
Àjò 'yí a kì í m'áya ẹni lọ,
Àjò àrèìbọ̀!
Ìwọ Olùfẹ́aiyé, lọ de Bẹ́rì k'o wò'yàwó rẹ,
Libi ó nìkàn sùn l'ájò àrèìbọ̀,
Àjò 'yí a kì í m'ọ́kọ ẹni lọ,
Àjò àrèìbọ̀!
Ìwọ Olígbàgbọ́-ẹnu, lọ dé Bẹ́rì k'o wò tibatiye rẹ,
Nwọ́n nìkàn sùn l'ájò àrèìbọ̀,
Àjò 'yí a kì í m'ọ́mọ ẹni lọ,
Àjò àrèìbọ̀!
Ìwọ Olùfẹ́aiyé, lọ dé Bẹ́rì k'o wò ọmọ rẹ,
Libi ó nìkàn sùn l'ájò àrèìbọ̀,
Àjò 'yí a kì í mú tibatiye ẹni lọ,
Àjò àrèìbọ̀!
Ìwọ Olígbàgbọ́-ẹnu, lọ dé Bẹ̀rì k'o w'ẹ̀gbọ́n rẹ,
Libi ó nìkàn sùn l'ájò àrèìbọ̀,
Àjò 'yí a kì m'àburò ẹni lọ,
Àjò àrèìbọ̀!
Ìwọ Olùfẹ́aiyé, lọ dé Bẹ́rì k'o w'àbúrò rẹ,
Àjò 'yí a kì í m'ẹ́gbọ̀n ẹni lọ,
Àjò àrèìbọ̀!
Ìwọ Olígbàgbọ́-ẹnu, lọ dé Bẹ́rì k'o wo olùfẹ́ rẹ,
Libi ó nìkàn sùn l'ájò àrèìbọ̀,
Àjò 'yí a kì í m'ólùkù ẹni lọ,
Àjò àrèìbọ̀!
Ìwọ Olùfẹ́aiyé, lọ dé Bẹ́rì k'o w'olùkù rẹ,
Libi ó nìkàn sùn l'ájò àrèìbọ̀,
Àjò 'yí a kì m'ólùfẹ́ ni lọ!
Ìwọ Olígbàgbọ́-ẹnu, o kò ńwòran i?
Ìwọ Olùfẹ́aiyé, o kò ńrí gbogbo rẹ̀ i?
Bí Ọlọ́run bá dá ọ sí lònì,
Lọ wò 'yí o bí ń'nú 'yí ti lọ láìmẹ̀ṣẹ̀.
Bí Ọlọ́run bádá ọ sí lònì,
Má rò pé 'wọ á wà d'ọ̀la, ọjọ́ èniyàn kò gùn.
Ìwọ dẹ̀ rí àwọn Dàdí-Màmí wa i?
Dede wọn ti r'ẹ̀hìn-ẹ̀kù,
Ng kò dẹ̀ wí ti wẹ́wẹ̀ẹ̀wẹ́ ọmọ-ẹ̀hìn.
Pipẹ́ rèé ó máa pẹ́, àgbọ̀nrín á bọko,
L'ájò àrèìbọ̀!

Mose Lijadu Awon Arofo - Orin Sobo Arobiodu (Macmillan Nigeria Publishers Ltd, Lagos and Ibadan 1974)